# ÌSÒFIN ÀFỌWIFÙN TI ÒMÌNIRA 2011

## Freedom of Information Act, 2011

# ISỌIWAJU

# (FOREWARD)

Gẹgẹ bi o se wa ni akọsilẹ ninu ofin ile igbimọ asofin agba ni odun 2011 ominira fun ise ofin ọrọ sisọ fẹ ki gbogbo ọmọ orile ede Naijiria ni ominira ti o muna doko si ọrọ sisọ gẹgẹ bi o se yẹ lati ọdọ ijọba. Ninu awọn ohun ti wpn ro pe yoo jẹ anfaani rẹ ni a ti ri iwọnyi-lati.

- Ri i daju pe eto ijọba jẹ ti gbogbo eniyan.
- Jẹ ki isẹ ijọba, si silẹ fun ọfin toto lati ọdọ ẹnikẹni
- Ki a fi ara mọ awọn ilana gbogbo ti a ti la silẹ.
- Jẹ ki imọgaara ati isiro owo ja geere ninu eto ijọba.
- Ki opin le de ba iwa ibajẹ, ati
- Jẹ ki gbogbo ohun igbẹkẹle wa ni ọpọ jantirẹrẹ fun itẹlọrun gbogbo ara-ilu.

Gbogbo eyi ni yoo ja si asan ayafi igba ti gbogbo nnkan ti ajọ ominira fun ise ofin ni lọkan ba to ye gbogbo eniyan ti wọn si mu-un sa loogun gbogbo awọn ẹgbẹ ti o mọyi ito lẹsẹẹsẹ isẹ iransẹ, sakaani ati isojuẹni ti o pọn dandai fun labẹ ise ofin lati se ojuse kọọkan bi o se yẹ.

Ohun ti o se pataki ni wi pe ofin yoo wa ni ailo ati pe o di igba ti a ba se amulo rẹ ki o to ni amuyẹ, eyi ko yọ ajọ ominira fun isẹ ofin fun ọrọ sisọ silẹ rara o jẹ ohun ti o wulo pe ki awọn ọmọ orilẹ-ede Najiria ti ofin wgn si wa fun ni imọ ti o muna doko lori ohun ti awọn ofin naa da le lori, ọgbọn inu wọn, erongba wọn ati anfaani ti wọn le ri ninu lilo iru ofin bẹẹ, ati pelu ohun ti yoo jẹ adanu wọn bi wọn ba lu ofin ati gbogbo ojuse tio yẹ ki wọn se pelu.

Idi eyi ni o, fa ti, Ajọ idani-lẹkọ, ati iwadii ẹtọ lati mọ pẹlu ibasepọ amyn ajọ ati igbimọ orisi-risi lati oke okun fi gbagbọ pe o yẹ ki a polongo agbekalẹ ajọ ominira fun ise ofin fun ọrọ sisọ, fun idi eyi, ominira fun isẹ ofin fun ọrọ sisọ, fun idi eyi, ominira fun isẹ ofin fun ọrọ sisọ ti wa ni titumọ si awọn ede orilẹ-ede Naijiria mẹtẹẹta; Yoruba, Igbo ati Hausa. A ti se afihai ọpọlọpọ atunkọ ati atuntẹ, bẹ ẹ si ni a o pin-in fun gbogbo eniyan ni Naijiria, lara erongba ikede yii ni a ti ri iwọnyi lati:-

- Jẹ ki awọn ara ilu mọ nipa ipese ajọ ominira fun ise ofin fun ọrọ sisọ.
- Gba awgn ara-ilu ni iyanju ati lo ẹtọ wọn labẹ ofin lati gbọ ọrọ lati ọdọ ijọba agbegbe.
- Gba wọn ni iyanju nipa ifihan gẹgẹ bi o se wa ni abẹ ise ofin.
- Se aridaju ipese awgn agbekalẹ fun gbogbo eniyan gẹge bi o se wa ni abẹ ofin.
- Ri aridaju pe awgn asoju idanilẹkọọ sa ipa wọn lati tar imọlẹ si ise ofin naa pẹlu.

Lati se aseyọri erongba yii agbekalẹ ẹkọ lorisiirisi ti wa fun awọn alaboojuto ipinlẹ ati olori ajọ ti on se asoju idanilẹkọọ kọọkan.

Awọn olusọ yoo gbe igbesẹ si ọdọ olori ti o n danilẹkọọ nipa eto ti ko le yipada ni ipinlẹ kọọkan. Awọn olori idanilẹkọọ ni ayipada yoo gbe igbesẹ lati rifi wi pe awọn olusọ ati awọn ara adugbo kọọkan fi ara wọn silẹ lati ijọba agbegbe wọn.

Idakeji eto yii yoo waye ni ijọba ibilẹ kọọkan yoo se amulo idagbasoke nipase, ere ati ibanisọrọ. nigba ti a dupẹ gidigidi lọwọ alamojuto eto ati awọn oluranlọwọ wọn fun iranlọwọ ai-dibajẹ wọn. Emi ko ni iye meji ninu ọkan mi pe gbogbo ọmọ orilẹ ede Naijiria yoo lo anfaani yii lati fun ipo ijoba awarawa ni agbara ati mimu wa si eto isejọba to ja gaara tirẹ lati mọ ni tirẹ lati gbe se ohun ti o tọ.

Beere lati mọ

Tirẹ lati mọ; ni etọ rẹ lat gbe ite aye se ohun ti o tọ:

Adupẹ

MIKE OMERI

Director General, NOA

## OFIN OMINIRA LATI LE SỌ ỌRỌ TI ODUN 2011

## FREEDOM OF INFORMATION ACT, 2011

## ALAYẸ LORI IWE IRANNILETI

### EXPLANATORY MEMORADUM

Ise ofin yii mu ki gbogbo eniyanmọ ọrọ lọfẹ ki ọ si pese fun gbogbo eniyan lati ni arfaani atisọ ọrọ, lati daabo bo eriyan gbogboboo, ki wọn ki o le dwo sinsin pẹlu ifẹ ati idaabobo onikaluku, lati daabo bo gbogbo awyn osisẹ ijọ ba nigba ti wyn ba sọ awyn ọrọ asiri jade lai gba asẹ ki o le mu asetan Pataki wa.

# ÌSÒFIN ÀFỌWIFÙN TI ÒMÌNIRA 2011

**Freedom of Information Act, 2011**

# ÒFIN ÀPAPỌ̀ ILẸ̀Ẹ NÀÌJÍRÍA

## Arrangement of Sections

Ààtò Lábalalábala


1. Ìlẹ́tọ̀ọ́ sí àkọsílè.
2. Àfọ̀wifún nipa ààjọ-ìsọnà ìlú.
3. Bíbèèrè fún àǹfàní sí àkọsílè.
4. Àkókó fún ìjẹ́tẹ́wọ́ gbà tàbí àìjẹ́tẹ́wọ́ gbà ìsèbéèrè fún àkosílè.
5. Títàtaré ìsèbẹ́ẹ̀rẹ̀.
6. Sísún ìwọ̀n àkókò ìsèbéèbè  àkọsílẹ̀ láti jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà tàbí àìjẹ́tẹ́wó gà.
7. Bí a kò bá fúni láàǹfàní.
8. Ẹsan.
9. Ìtójú àti ìpamọ́ àkosílẹ̀.
10. Bàjé tàbi se àmúlúmálà àkosílẹ̀.
11. Bì ìbójútó tàbí àtilẹ́yìn ìdásí àgbáyè bá kúrò.
12. Bí ìgbófinro àti ìtọpinpin bá kúrò

13. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwon òsìsẹ́ lórí ìláánfánì sí àfọ̀wífún àti fífí ìsófún yìí lélẹ̀ dóju-iwọ̀n.
14. Bí a bá yọ àfówífún ara ẹni kúrò.
15. Bí a bá yọ àfọ̀wífún alárenà kúrò
16. Bí a bá yó ìwóye-ẹni tàbí àǹfání mìíràn tí a rí gbà lábẹ́ òfin kúrò
17. Bí a kò bá se àmúlò ẹ̀kọ́ tàbí ìwé-ìwádìí
18. Onírúuru-òye
19. Bí ààjọ̀-ìsọ̀nà bá kò láti yọ̀ǹda àkọsílẹ̀
20. Àgbéyẹ̀wo ilé-ìpẹ̀jọ́
21. Àgbéyẹ̀wo-ẹjọ́ ní sókí
22. Àǹfàní sí àfòwífún lati owọ́ ile-ejo.
23. Kí ile-ejo sọ́ra fún ìmúdànilójú
24. Aibale oka lori
25. Asẹ lati yọ̀ǹda àfòwífún
26. Àwon iwe-aseranwọ́ ti a yọ kúrò
27. Ààbò àwọn òsisẹ́ ijoba
28. Àkopo-ìwé tí a tò lékèka-ò-jèka
29. Ìjíyìn àbálọbálọ̀
30. Ìsègbè mìíràn
31. Ìládìí-àfọ́ (Ìlàdìí-afò)
32. Ìtọ́kasí

# ÌSÒFIN ÀFỌ̀WÍFÚN TI ÒMÌNIRA 2O11

## ÒFIN ÀPAPỌ̀ ILẸ̀ Ẹ NÀÌJÍRÍA

Ìsòfin tí se láti mú àkọsílẹ̀ àti àfọ̀wífún alájoni le wà ní àrọ́wọ́tó, kí ó le rọ gbogbo ènìyàn lòrún láti rí àkọsílè àti àfọ̀wífún gbà, lári dáàbò bo akosile láti àfòwífún ìlú lọ́nà tí kò fi ní se ìlòdì sí ìgbaye-woye gbogbo èniyàn àti enikooka àti láti daabo bo àwọn osisẹ́ ijoba ni àsìkò tí wọ́n bá yòǹda àfowífún lai gba ase tàbí alakale tó ye fún irufẹ́ isẹ́ bẹ́ẹ̀, àti àọn isẹ́ mìíràn to o fi are pe ẹ.

**Ọjọ́ 28 Osù Èbìbì, 2011**.

Èyí tí a fi leie lagti ọwọ́ ọ Ìgbìmọ̀ Apapo Ijoba Olómínra Naijiriya.ò

1. (1) Bí ó tlẹ jẹ pe a rí nǹkan kan ninu isofin, ofin beere fún afowifun, yálà tàbí ó wa ni kikosile, tí ó wà nó òsìsẹ́ ìjoba, àgbodegba tàbí ààjo-isọ̀na, ti a dàsìle.

   (2) Eni ti o n sebeere ko níílo láti fi imọ̀ssílara ìwoye rè hàn nigba ti o ba n béère fún afowífún

(3) Ẹnikẹnì tó bá lẹ́téọ̀ọ̀ sí afowífún labe isọ̀fun yìí le pe aajo-isona ilu lejo lati se gẹ́gẹ́ bí isofun yii se fi lélẹ̀.

2. (1) Aajo-isona ilu gbodo rii daju pe o se akosile ati itoju igbòkègbodo, ise àti okò-wò rẹ̀

(2) Aajo-isona alajonig bodo rii daju pe o se aato ati itoju to peye fún gbogbo àfọ̀wífún ti o ba ni akata rea lona ti yoo fun gbogbo eyiyan lati lò.

(3) Ààjo-isona alajonig gbodo rii pe oun se itewe awon afowifún wonyi ni ibamu pelu isomogbe (4) Tí abala yìí --

(a) Apejuwe aajo ati ekunrere nipa aajo ise aajo-isona leleka-o-jeka.

(b) lẹ̀sẹẹ̀sẹ--

(i) Aato akosile to wa labe akoso aajo-isona fun ilaanfani ti afowifun labe isofin tii, ati

(ii) Ìwé-itoni ti àwon osisie aajo-isona n tle tabi se ise amuse.

(c) Ìsàpèjúwe àkópọ́-ìwé àbá tí ààjo ènìyàn lọ́wọ́-sí tàbí tàìlọ́wọ́ tòhun ti àsẹ ilé-ẹjọ́

(i) àlàkàlạ̀ tòótọ́ ti ààjọ-ìsònà

(ii) Àlàyé àti ìlàdìí-àfọ̀ lọ́rí ọ̀nà-àgbamúsẹ́se tí ààjo-ìsọ̀nà ń tẹ̀lé.

(iii) Mímúrasílẹ̀ fún ọ̀nà-agbàmúsẹ́se tó kẹ́yìn ìgbóríyìn àti ìpinu.

(iv) Àbálọbábọ̀ tòótọ́, bíbóju-inu wo àbálọbábọ̀ àti àyẹ̀wò bóyá isẹ́ ẹ ààjo-ìsọ̀na ni tàbí kìí se isẹ́ rẹ̀.

(v) Àfọ̀wífún tí ó níí se pẹ̀lú ìwè-ìdúnàádúrà tàbí ìnáwó ààjọ-ìsọ̀nà.

(vi) Orúkọ, owó-òyá àkọ́lẹ àti ọjọ́ tí a gba òsìsẹ́ ẹ ààjọ-ìsònà.

(vii) Ẹtọ́ ilú, gbogbo òsìsẹ́ àti àkosílè tó kẹ́yìn gbogbo ìbò tí wáyé ní ààjọ-ìsọ̀nà.

(viii) Orúkọ gbogbo òsìsẹ́ àti àkọsílè tó kẹ́yìn gbogbo ìbò tí ó wáyé ní ààjọ-ìsọ̀nà

(e) lẹ́sẹẹ̀sẹ--

(i) Akópọ̀-ìwé ìsèbéèrè isẹ́-àwọ̀sẹ, `asẹ, ìrànwọ́, ìwé-ìfààyéfún tàbí ífohùnsọ́kan.

(ii) Àbálọbábọ̀, àkópọ̀-wé, ìtọpinpin tàbí àtẹ̀jáde láti ọwọ́ abánisisẹ́ ní ààjọ-ìsọ̀nà, àti

(iii) Ohun-èèlò àfọ́wíún tó níí se pẹ̀lú owóóìrànwọ̀ láti ọwọ́ alagbàse fún isẹ́-àgbàse tàbí láàárín ààjọ-ìsònà sí ààjọ-ìsọ̀ìlú tàbí ààjọ-aládàánì mìíràn.

(f) Àkọ́lé àti àdírẹ́sì osìsẹ́ ààjọ-ìsọ̀nà ni gbọ́dọ̀ fi ránsẹ́ olùsèbéèrè lábẹ́ ìsòfin yìí, bí ààjọ-ìsọ̀nà bá kùnà làti se àtèjádè, ìkùná rẹ̀ kò ní di àǹfàní láti rí àfòwífún tí ó wà lákàtà rẹ̀ gbà.

(4) Ààjọ-ìsọ̀nà ìlú gbọ́dọ̀ rí I dájú pé àfọ̀wífún tí a mẹnu bà ní aballa yìí di tọ́rọ́-fọ́ nkálé, kí gbogbo ènìyàn sì mọ̀ nípa rẹ̀ lórísírísí ọ̀nà títẹ̀ sínú ìwé, ẹ̀rọ àti lórí ìtàkùn-ayélujára àti káàkiri àwọn – físì ààjọ-ìsọ̀nà bẹ́ẹ̀.

(5) Ààjọ-ìsọ̀nà alájọru yóó máa àgbéyẹ̀wò àti imúdójú-ìwọ̀n àfòwífún tì yẹ fún àtẹ́jàde lábé abala yìí lóòrékóòré, ati ni kete tí àypade bá wàyé.

(6) Ẹni tio ba lẹtòó sí àǹfàní tí ìsọ̀fín yìí là pe kale lè pe ààjọ-ìsọ̀nà aájọni lẹ́jọ́ láti se gẹ́gẹ́ bí abala yìí se fi lẹ́lẹ́.

(7) Ẹ̀ka ìgbófínró, ìsòfín tàbí ìdájọ́ tó jẹ́ ti ààjọ-ìsọ̀nà alájọni jẹ́ aláse, alákòóse ẹ̀ka alábbójútó ìjoba ati awon tí á dásílẹ̀ pẹ̀lú àtìlẹ́yìn òfin àti gbogbo ilẹ́-ìsẹ́ tí ìjọba ń tukọ̀ rẹ̀, tí wọ́n sì ń sisẹ́ ìlú tàbí sisẹ́ sin ìlú.

3. (1) Bìbéèbè fún àkọsílẹ̀ tàbí àfọ̀wífún lábé isofin yìí gbódò wà ni ìbámu pèlú abala ìsọ̀fin yìí.

(2) Èrèdí-ìsòfin yìí nip e ijoba tbi aajọ-sọna ni yóó máa se àkóso tó ye lórí àfọwífún tàbí àkọsílè tí a beere fún lábé isofin yii ti ko si ni ni tite sugbon nipase erọ

(3) Ẹni ti ko ni ìmó mooko-mooko abi alaabo-ara ko ni le beere fún àfọ̀wífún tàbí akosile labe isomogbe (1) ti abala yìí àfi nipase elomiran.

(4) Òsise ìjọba tabi aajọ-isona tí a fún ní asẹ yoo rii daju pe ibeere sebeere di kilosile ní liana àlàkalẹ lábẹ́ ìsomogbe (1) ti abala yìí ó sì tún gbọ́dọ̀ se ẹ̀dà se àfowifun náà nó ìlànà àkosílè fún olusebeere to fi ọ̀rọ̀-enu béèrè afowifun tabi akosilee.

4. Afowifun ti a bèèrè labe isofin ààjo-ìsọnà, yóó fi ori fún abala u, I atti isofin yìí, nibi tí a bá ti bèèrè fún afowifun laarinọjọ meje (7) ti isebeere ti je itewogbà—

(a) Je kí afowifun náà wa ni arowoto fun olusebeere

(b) Bi ààjọ-ìsọ̀nà alajọni ba gbero lait ma gba isebeere laaye, aajo-isona yoo kowe so fun olusebeere wi pe oun kò ní le yonda gbogbo tabi apa kan afowifun naa fún olusebeere , yóó si sọ idi ati abala ti isofin yiigunle to mu ko isebeere.

5. (1) Bi aajọ-isona ijoba ba yonda afowifun fun olusebeere, bi o ba si rìi pé ààjọ-ìsọnà alajoni miiran ni iwoye-ero to ga julo si irufe afowifun be aajo-isona ti a ti bèèrè fún afowifun ojo meta (3) si ojo meje (7) leyin ti je ite le ite le tatare isebeere fun olusebeeree nipa ako-sile, ni eyi ti yoo je ki asebeere mọ pé ile-ejo le se agbeyewo re.

(2) Nibi ti a ba ti tatarè isebèèrè labe isomogbe abala (1), a o ri gege bi èyí ti a ti owo aajọ-isona alajọni tatare rè ní ọjọ́ tí o tó wọn lọ́wọ́.

(3) Nitori isomogbe

(a) aajọ-isọnà ìjọba yóó ti sọ bóyá àfọ̀wífún tàbí akosile ewa.

(b) Bi a ko ba seda afọwifun ni tabi fun aajo-isọna ilu, ajọ isọna yii ni yoo yẹ ajo-isọna akọkọ ti yoo ri afowifun naa gba.

6. Ajọ isọna ilu le sun iwọn aye ki abala karun (5) tabi abala keta (6) fi lelẹ niwọn ọjọ meje (7) bi.

(a) Akosilẹ ti a bere fun ba kọ, iwọ ọjọ ti aajọ-isona ilu ti yan tẹlẹ.

(b) Apero yoo se iranwọ fun isebeere lati pari ni iwọn asiko ti o yan tẹle, wọn yoo si fi ọrọ ranse si olusebeere pe ẹtọ rẹ ni lat wifun.

7. (1) Nigba ti ijọba tabi ajo-isọna ilu ba kọ lati funni ni anfaani lati bere fun akọsile itabi afọwitun labẹ isofin yìì, yoo san ẹtọ ti ẹni naa ni lati yẹ ipinnu aajọ -isọna wo lori aijẹ-itewogba isebeere re, ki ite-ejo fig be e ye wo.

(2) Pipeni si akiyesi fun kiko lati je ki eniyan ri afowifun tabi akosile gba yoo koko ami ati ifowosi reyi ti yoo se atoka awo to lowo si iwe-ikofun.

(3) Isomo gbe kini (1) ti abala yii ni ijọba tabi ovajo-isona ijoba yoo ti so boya atowifun tabi akosile wa.

(4) Nibi ti ijoba tabi aajo-isọna ba kuna lati yonda afowifun, tabi akosile ti a bèèrè fúnlabe isofin yìí tabi lára rẹ̀ níwọ̀n àsìkò tí ìsọ̀fin yìí fi lẹ́lẹ́, nítorí ìsọ̀fin yìí, ààjọ-ìsọ̀nà ni a ó rí gẹ́gẹ́ bí adinagboogun.

(5) Níbi ti won ba ti ko lati yonda anfani lona aito, òsìsẹ́ tabi aajo-isona ti ajere esun yii ba si le lori yóó san owo itanran ₦ 500,000.00

8. Owóìsebéère fún ẹ̀dà akopo-iwe yóó wà ni odiwọn-àjọhùn

9. (1) Ìjọba tàbí ààjọ-ìsọ̀nà ijọba gbọ́dọ̀ rìi pé ó se itoju gbogbo afoeífún tabi akosílè isẹ́ òsisẹ̀ ìgòkègbodò àti nǹkan mìíràn tó se pàtàkì tàbí tí ó níise pẹ̀lú àfọ̀wífúnn tàbí àkọsílè ààjọ-ìsọ̀nà.

(2) Ìjọ̀ba tàbí àajọ-ìsọ̀nà gbọ́dọ̀ ríi pé gbogbo àfọ̀wífún tàbí àkọsílè to wa lákàtà rẹ̀ wà letoleto àti ní ìpamọ́, lọ́nà tí yóó fi ará-ìlú láti jẹ àǹfàní wọn lábẹ̀ ìsòfin yìí.

10. Ẹ̀sùn tó ràni láwọ̀n ọdún kan ni. Yálà òsìsìẹ́, tàbí olòrí-ìjọba, tàbí ààjọ-ìsọ̀nà alájọni ní ìbámu pẹ̀lú Ìsòfín yìí, to o ba finufindọ ba èyíkeyii àkọsile tó wà ní àkàtà rẹ̀ jẹ́ t`abí bí ó bá gbìyanju àmúlùmálà kí ó tó fi fún ẹnikeni ààjọ tàbí àkòpọ́ àwọn ènìyàn agbègbè tí ó ń bèèrè fún un.

11. (1) Ààjọ-ìsọ̀n le kọ̀ ,láti fúni ní àfọ̀wífún tí ó lè daa omi àwùjọ rú àti ààbo Ìjọba

Àpàpò Olómìnìra Nàìjíría.

(2) Bí ó ti wù kó rí pẹ̀lú ìsọmọgbe (i), a kò gbọ́dọ̀ kọ̀ láti fúni àfọ̀wífún níwọn ìgbà tí ìwòye àwùjọ ènìyàn bá rékọjá ewu tó le tẹ̀yin rè yó.

12. (1) Ààjọ-ìsọ̀nà loe ko láti fúni ní àfọ̀wífún tí ó bá jẹ́ pé—

(a) Àkosile tí a kójọ fún sise àkóso ààjọ-ìsọ̀nà alájọni àti tí ìgbófìnró tàbí ààjọ alatunnuse ìgbófínró tàbí ọ̀rọ̀ abanu, súgbọ́n ní ọ̀nà tí fífúni yóó.

(i) Dá sí ìdánuduro tàbí àrítọ̀kasi àti àti àsàrò òfín tó lóye láti ọwọ́ agbófinró tabi ààjọ alátùn-únse

(ii) Dásí ìdánudúró ìpàdé ìmòfínro lati pawọ̀ ààjọ-ìsọ̀nà alájọni

(iii) Kọ̀ láti gba ènìyàn lááyè fún ìdájọ́ òdodo tàbí fún sise àwíjàre.

(iv) Àìsọ ohun ìkọ̀kọ̀ tara-ẹni di mímọ̀.

(v) Se àkópọ̀ mọ̀-sínú-mọ̀síkùn tara-ẹni lábẹ́ ẹ abala ẹ́ú ti Isòfín yìí, àyàf, bí a bá máa rí ohun tíí se ti gbogbo ènìyàn gẹ́gẹ́ bí nǹkan tó se pàtàkì jùlọ ni a ó yòǹda àkọsílè náà,kíkọ̀ fúni kò ní se ese, àti pé.

(vi) Yóó tako ìtọpinpin arúfín tó bá ń lọ lọ́wọ́.

(b) Fífún ní àfọ̀wífún le kó ijiya bá àwọn alásẹ agbófínro.

(2) Bí nǹkan mìíràn tile jẹyọ ní abala yìí, kò tó láti má sàì gba ìsèbéèrè bí ìwòye àwọn ènìyàn láti yọ̀ǹda afowifún ba rekoj ìpalata tó le tèyìn rẹ yó.

(3) Aajọ-isona naa kọ lati fun-ni ni afọwifun bi o le fa ilodi-isofin.

(4) Nítorí abala (1)(a), “àpérò olóǹtẹ̀” túmò sí ìtọpinpin ti—

(a) Ò níí se pẹ̀lú ìsàkóso tabi r ìsòfin, òfin, tàbí àlàkalẹ̀-ìse lágbạra;

(b) Ró lágbára tàbí se é fún yálà ìsọ̀fin, òfin tàbí àlàkaẹ̀.

13. Gbogbo ìjọba tàbí ààjọ-ìsónà alájọni gbodo rí I pé wọ́n sw idánilẹ́kọ̀ọ́ tó yẹ fún awon òsise rè lórí ẹ̀tọ́ ará-ìlú nipa àfọ̀wífún tàbí àkọsílè tó wà lakata ìjọba tàbí ààjọ ìsọ̀nà àlájọni gẹ́gẹ́ bí ìsòfin yìí se tọ́ka rẹ, tí ó fi lérẹ̀.

14. (1) Forí fún ìsọmọgbè (2) Bí ìsèbéèrè bá ní àfòwífún olúkúlùkù tàbí èyí tí ìsọmọgbè yìí yọ sílẹ̀, ààjọ-ìsọ̀nà yóó kọ̀ áti gba ìsèbéèrè fún àfọ̀wífún.

(a) Àkópọ̀-ìwé àti àfọ̀wífún tí a tójú nípa oníbàárà, aláìsàn, olùgbélé, túúlẹ̀, tabi ààjọ afiyaẹni lori ilodi sí òfin.

(b) Akopọ-iwe osisẹ ati afọwifun olukuluku ti tọju nipa osisẹ amusoju tabi asoju ni asẹ labe asẹ ti ajọ-isọna ilu tabi olusebeere ipo bẹẹ ẹ.

(c) Akopọ iwe ati afowifun olukuluku ti a tọju nipa olusebeere, abẹwẹ-akọlẹ abi eni-afun lasẹ lati ọwọ ijọba tabi aajo-isọna ilu to fọwọsowọpọ yala pẹlu tabi to n se isẹn-ipe tabi isẹ oojọ lari iforukọsilẹ, ifunni-lase tabi itonilọna.

(d) Lai jẹ pe ase beere fun afọ̀wifún mpasẹ ofin, afọwifun ti eni ti n san owo ori nilo yoo jẹ mọ ibufun ati ikojọpọ awo ori,

(e) Afowifun to tokoi irufe ẹni to beere fun ifisun tabi pese afọwifun eeto isakoso, itọpinpin, igbofinro tabi aajọ afiya-jẹni lori ilodisi ofin.

(2) Ààjọ-ìsọ̀nà alájọni máa yọ̀nda afọ̀wífún olukuluku bí—

(a) Olukuluku tí wọn yóó bèèrè bóyá kí wọn yọ̀nda àfowifun, tabi

(b) Àfọ̀wífún tí ó wà ní àrọ́wọ́tọ́ gbogbo ènìyàn àwùjọ

(3) Ibí ìyọ̀nda àfọ̀wífún bá ń sègbè fún ìlọ́wọ́sígbogbogbòò, bí ìlọ́wọ́sí gbogbogbòò bá sì rékọjá, ti ẹni kọ̀ọ̀kan tí o ǹ bèèrè fún afowífún tó forí-fún abala 14(2) ti Ìsòfin yìí.

15. (1) Ààjọ-ìsọ̀nà alájọni yóó tí àfọ̀wífún bá ní—

(a) Àsiri inaja àti idunaadura, tàbí inawo-nájà tí a rí gbà lọ́wọ́ ẹnikan tabi olókòwò-aalásirí tàbí ọjà olonte, àǹfàní tàbí ohun-ipamọ́, nibi tí irúfẹ́ títú asírí ìnájà tàbí afowifún béè le mú ifàsẹ́yìn bá ìfẹ́ ẹlòmíràn tí kò ba si le se ìdíwọ́ eniyan tàbí okòwò tá a fẹ́ se àfihàn.

(b) Sísọ àfọ̀wífún di mímọ̀ le fa ìbẹ̀wépẹ̀jẹ̀jọ́ tàbị mú àyọjúràn lórí ìdúnáàdúrà ẹlòmìràn wá.

(c) Àbá àti ìfàsẹ̀fún iséàgbàse, owó-ìraànwọ́, tàbí ìfohùnsọ̀kan, pẹ̀lú àfọ̀wífún ní èị fòóró tàbí fún ẹnikẹni ní aǹfàní bí ó ba di mímọ̀ gbogbo ènìyàn

(2) Ààjọ-ìsònà alájọni, bí sì-m-gbè tilẹ̀e kọ̀ láti yọ̀nda díẹ̀ nínú àkọsílẹ̀ lórí èsì tábi àyẹ̀wò tàbí abajade yòẹ̀wo agbejade tí ààjọ-ìsona alajọni gbé jade fúnra wón tabi láti ọwọ́ eleomiran

(3) Níbi tí ààjọ díẹ̀ nínú rẹ̀, yeí tó ní ààfọ̀wífún, tàbí dẹ̀ nínú rẹ̀, èyí tó ní àbájade èsí àyèwó àgbegbé, ní àsìkò kan náà tí aajọ-ìsọ̀nà bá ti yọ̀ǹda afowífún tàbí diẹ lára rẹ̀ ni yóó kọ́wé sọ fún olùsèbéèrè nípa ọ̀nà-ìtọ̀sẹ̀ tó gbà se ayewo náà.

(4) Ààjọ-ìsọ̀nà alájọni yóó le yọ̀ǹda èyíkéyìí àfọ̀wífún tí ìsọmogbe(1) mẹnu bà ni abala yìí tí ó bá wà ní ibámu pẹ̀lú ìlọ́wọ́sí gbogbogbòò tó jẹ mọ́ ètò-ìléra, ààbó, tabi didaabo bo àyíká , bí ìlọ́wọ́sí gbogbogbòò bá sì réjọká àǹfàní tí a le rí ài lera laaye kan tàbí lọ́wọ́sí nípa ìbẹ̀wẹ̀-pẹ̀jó láàyè ka tàbí lọ́wọ́sí nípa ìbẹ̀wẹ̀ – pẹ̀jọ́ tabi idunaadura mìíràn

16. Ósọ̀nà àjọse lè kọ láti yonda àfọ̀wífun tí ó bá forí àǹfàní wọ̀nyí

(a) Àǹfàní oníbààrà-agbẹjọ́rò
(b) Àǹfàní oníbààrà-onísẹ́ ìlera
(c) Àǹfàní oníbààrà isẹ́-ìròyìn
(d) Àǹfàní oníbààrà tó seé fọkàntẹ̀ nípasẹ̀ ìsòfín

17. Ìsọ̀nà àjọse le kọ láti yọ̀ǹdaa àfọ̀wífún tí ó ní ìt/onà-ẹ̀kọ́ tàbí élò isẹ́-ìwádìí láti ọwọ́ ọmọ ẹgbẹ́ káà.

18. Bí a tile àlàkalẹ̀ mìíràn nínú Ìsòfín yìí, nibi tí a bá ti bèèrè fún àfọ̀wífún láti ọwọ́ ìsọ̀nà àjọse tí Ìsòfín yìí kọ yíyọ̀ǹda rẹ̀, ìsọ̀nà yóó le yọ̀ǹda lára àfọ̀wífún tí ase òfin kò gbẹ́gidínà

19. (1) Ìsọ̀nà alájọni le kọ̀ yọ̀ǹda àfọ̀wífún tó níí se pẹ̀lú—

(a) Ìbéèrè ìdánwò-ránpẹ́, kọ́kọ́rọ́ ìsìrò àti àwọn détà ìdánwò mìíràn tí a lè fi se ètò ìdánwò isẹ́-akadá tàbí lò láti se lò se ìpìnnú bóyá olùsèbéèrè peregedé láti fún ní ìwé-àsẹ tàbí gbà sí isẹ́.

(b) Òǹmètò-ìkọ́lé àti onímọ̀-ẹ̀rò gbogbo tàbí lára àpẹẹrẹ ìlé tí a ń kọ́ pẹ̀lú owó alájọni, ní èyí tó jẹ́ pé yọ̀ǹda àfọ̀wífún rẹ̀ yóó pagidínà ààbò; àti

(c) Ìsirò ìlé-ìkàwé àti àwọn àkọsílẹ̀ mìíràn tó ń tọ́ka àwọ èèlọ́-ìwé fún òǹkàwé

(2) Bí a tile rí nǹkan mìíràn ní abala yìí, a kò ní kọ bíbèèrè fún àfọ̀wífún bí ìlọ́ wọ́sí gbogbo ènìyàn láti yọ̀ǹda rẹ̀ bá rékọjá ìpalára tí ó lé fà.

20. Olùsèbéèrè tí à bá kọ̀ láti ní àfọ̀wífún, tàbí lára rẹ ẹni bẹ́ẹ̀ lè ìsọ̀nà alaájọni lẹ́jọ́ lórí ọ̀ràn náà láààrín ọgbọ̀n èò ọjọ́ lẹ́yìn tí a ti kọ̀ láti gbàá láàyè tàbí kọ̀ fún un, tàbí lẹ́yìn ọjọ́ tí ilé-ẹjọ dá tàbí gbà láàyè.

21. Ìsèbẹ́ẹ̀ lábẹ́ abala 20 ni a ó fetsí tí a ó sí fi òté lé ìsọnísókí rẹ̀

22. Bí a tile sí ohunkóhun tí ó tako ìsòfin Ẹ̀rí, tàbí àlàkalẹ̀ tí a se lábẹ́ rẹ̀iléọ̀ẹjọ́ le, se àgbéyẹ̀wò àfọ̀wfún tí ó bá ìsòfin lọ, nínú ìpàdé-àjẹmófín kí ó tó di pé asèbéèrè fún un lábẹ́ abala ẹ̀ò ti Ìsòfin yìí, ìyẹn lábẹ́ ìsọ̀nà alájọni, kò sì se é láti má yọ̀ǹda àfọ̀wífún fún ilè-ẹjọ́

23. Níbi ìpàdé ajẹmófin tí ó jẹyọ látàrí ìbèèrèfún lábẹ́ abala 20 ní ilé-ẹjọ́, yóó sọ́ ra, títí

kan ìgbà tó yẹ, ònjinmi-ìmọ̀ asoju, ki won ssi se ejọ́ náà ní ojútáyé láti pagidínà. Síse iyonda àfọ̀wífún nipase ile-ejo tabi enikeni, ni èyí tí a ó sì pa à ní àsẹ fún isọna alajọni láti yọ̀nda àfọ̀wífún tí a sèbéèrè fún.

24. Níbi ìpàdé-ajẹmófín tí ó yẹyọ làtàrí ibeere fun labẹ́ abala 20, ipinnu ìsọ̀nà alájọni láti yọ̀nda tàbí kọ ìsèbéèrè fún àfọ̀wífún yóó dá lórí ìsọ̀nà alájọni tí ọ̀rọ̀ kàn.

25. (1) Bí ìsọ̀nà alájọni bá kọ sebéèrè fún àfọ̀wífún, nípasẹ̀ àlàkalẹ̀ Ìsọ̀fin yìí, ilé-ẹjọ́ yóó pa á ní àsẹ fún ààjọ-ìsọ̀nà lásẹ lati pagidínà àfọ̀wífún.

(a) Bí ilé-ẹjọ́ mọ̀ wí pé a kò fún ààjọ-ìsọ̀nà lásẹ lati pagidínà àfọ̀wífún.

(b) Tí ààjọ-ìsọ̀nà bá gba àsẹ, àmọ́ tí ilé-ẹjọ́ ríi pé kò tó fún ààjọ-ìsọ̀nà láti ísèbéèrè, tàbí

(c) Tí ile-ẹjọ́ bá se ìwádìí tí ó sì ríi pé ìlọ́wọ́sí ara ìlú fún yíyọ̀nda àfòwífún rékọjá, tí ó sì se pátàkì jí ki wọ́n kọ láti yọ̀nda àfọ̀wífún náà, lábẹ́ àkósó-bó-ti wuọkó rí.

(2) Èyíówù àsẹ tí ilé-ẹjọ́ lè dá nitorí abala yìí forí fún okun tí iru ẹjọ́ tí ilé-ẹjọ́ bá dà.

26. Ìsòfin yìí kò bá ìse lọ pẹ̀lú—

(a) Ìwé àtẹ̀jadé tabi ìwé tó wà fún títà fún gbogbogbòò.

(b) Ohun-èlò ile-ikawe tàbí Ilé- ìsura ìsẹ́mbáyé ti a se tàbí rà tí a si selọ́jọ̀ fún ìtọ́ ka tàbí ìpàtẹ.

(c) Ohun-èlò ti a fi si ilé-ìkàwé Àpàpọ̀, Ilé-Ìsúra-Ìsẹ̀mbáyé Àpàpọ̀ tàbí ilé-àkọ́pọ̀-èlò Àpàpọ̀ aládàáni ti Ìjọba Àpàpọ̀ Olómìnira Nàìjíríaláti ọwọ́ ẹnikeni tàbí ààjọ mìíràan yàtọ́ sí ìjọba tàbí ààjọ-ìsọnà alájọni.

27. (1) Bí ó tile jẹ́ pé a ri èyíkèyí ohunkohun nínú àkọ́jọ̀-òfin arufin, akọjọ-òfin ìjìyà, ìsòfín ìkọ̀kọ̀ lábẹ́ àsẹ, tàbí èyíkèyìí àsẹ, kò sí ìfínjà tàbí ìpẹ̀jọ́ arúfin tí yóó se lòdì sí ẹni bẹ́ẹ̀ fún yíyọ̀ǹda èyíkèyìí àfọ̀wífún pẹ̀lú èrò rere, tàbí èyíkèyìí lára ìlépa ìsọ̀fin yìí, fún ìjásí tó le jẹyọ nípa yìyọ̀ǹda, àbí fún kikùnà láti se ìfítóniléti tó yẹ lábẹ́ ìsọ̀fin yìí, bí ìfítónilétí tó yẹ bá di sise.

(2) Ko si oun ka ti o wa mnu akojọpọ arufin tabi isofin ikọkọ labẹ asẹ ti yoo se akoba fu ẹnikẹni osisẹ ilu to yonda afowifun lai gba asẹ sugbọn ti o se bẹ ẹ ni ero wipe.

(a) Lilodi eyikeyi ofin, alakalẹ tabi atẹle.

(b) Si dari, na ina-apa, seru, ati ilo agbara lọna aitọ; tabi

(c) aridimu ati ewu kan pato ti eto-ilera ilu tabi aabo bi o tile je pe yiyonda afowifun bẹ o ba ilakalẹ̀ isofin yíí mu.

(3) Ko si ifija abi ipẹjọ arufun ti yoo se atako ẹnikẹni to ba gba afowifun naa tabi ti o sit un yọnda re siwaju si.

28. (1) Pẹ̀lú idaniloju pé àfwífún ti a fi pamó sí àkàtà ààjọ-ìsọ̀nà alájọni labe ìsọ́ ẹlẹ́ka-

ò-jẹ̀ka tàbí ti a se àkópọ́-ìwé leleka-òjẹka lọ́gangan ìtùmọ̀ ìsọ̀fin ikọ̀kọ̀ lábẹ́ àsẹ kò le se ìdíwọ́ fún olusebéèrè láti yọ̀nda rẹ̀. Lábẹ́ àlàkọ ilẹ̀ ìòfin yìí sùgbọ́n lọ́ pọ̀ ìgbà ló jẹ́ pé ààjọ-ìsọ̀nà ìlú ti a ti sèbéèrè fún àfọ̀wífún ni yóó se ìpìnnu bóyà irúfẹ́ àfòwífún tí mẹ́nu bà ni ní abala11, 12, 14, 15, 16, 17, 19, 20, tàbí 21 tí ìsòfin yìí.

(2) Bí ààjọ-ìsọ̀nà ìlú níbi tí ìsèbéèrè ti ìsọmọgbè(1) ti wáyé bá fẹnukò pé kìí se irúfẹ àfọ̀wífún bẹ́ẹ̀ ni a tóka sí ní ìsọmọgbè (1) a ó fún olusebeere laanfaní sí irú afowifun bee.

(3) Bí ààjọ-ìsọ̀nà ìlú, níbi tí ìsọmọgbè (1) tí a mẹnu bà ti wáyé , ti a sí pinnu pé irúfẹ àfowifun tí a mẹnu bà nínú àwọn abala ti a tọ́ka sí ní abala (i) yóó sí kọ́wé sọ fún olusebeere.

29. (1) Kì ó tó di tàbí ní ọjọ́ ẹ́ osù Èrèlè ọdọọdún, ààjọ-ìsọ̀nà ìlú kọ̀ọ̀kàn yóó fi àbálọbábọ̀ isẹ́ ọdun tó kọjá, tí ó sì ní

(a) Iye ìpinnu tí ààjọ`isọ̀nà ìlú bá fi ààyè gbà láti sèbéèrè fún àfọ̀wífún àti ìdí fún sise irúfẹ́ ipìnnu bẹ́ẹ̀;

(b) Iye ẹjọ́ ọ kòtẹ́milọ́rùn tí a pè fún lábẹ́ Ìsòfin yìí, àti ìdí tí ẹjọ́-kotemilorun kookan fi yori sí àìrí afowífún gbà.

(c) Àpèjuwe yálà bí ilé-ẹjọ́ se sàtìlẹ́yìn fún ìpinnu ààjọ-ìsọ̀nà ìlú láti má yọ̀nda àfọ̀wífún làbẹ́ bí ó ti wù kó rí àti àpèjúwe pàtó lórí ọ̀nà tí wọ́n gbà láti má yọ̀nda àfọ̀wífún.

(d) Iye ìsèbeerè fún àfọ̀wífún tí a dá dúró láti owọ̀ ààjọ-ìsọ̀nà ìlú kí ó tó di ọjọ́ 31 Osu Owẹ́wẹ̀ ọdun tó kọja àti pataki iye ọjọ́ tí isebeere naa lò títí di ọjọ́náà lọ́wọ̀ ààjọ-ìsọ̀nà ìlú.

(e) Iye tàbí ìsèbéèrè àfọ̀wífún tí ààjọ-ìsọ̀nà ìlú rí gbà tí wọ́n sì gbé ìgbésẹ̀ lé lórí

(f) Pàtàkì iyee ọjọ́ tí ó gba ààjọ-ìsọ̀nà ìlú láti sisẹ̀ lórí orísirísi àfọ̀wífún;

(g) Akọ́pọ̀ owó-ẹsan tí ààjọ-ìsọ̀nà ìlú alájọni rí gbà fún sìsẹ́ isẹ́ lórí ìsèbéèrè bẹ́ẹ̀

(h) Iye ojúlówó òsìsé ààjọ-ìsọ̀nà ìlú tí ó sisẹ̀ lórí isebeere fún àfọ̀wífún, àti àkópọ̀ iye owó tí ààjọ-ìsọ̀nà ìlú náà fún sise isẹ́ lórí ìsèbéèrè bẹ́ẹ̀.

(2) Olúkuluku ààjọ-ìsọ̀nà ìlú yóó ríi pé àbálọbabọ naa wa ni aro woto ara-ìlú, lorisirisi ọ̀nà bíì, ẹ̀rọ-komputa àti ẹrọ-gàá-sí-mi létí, bí ó bá si jẹ́ pé ẹ̀rọ-kọ̀mpútà àti ẹrọ-gàá-sí-mi létí kò bá tíi rí sẹ́ẹ́ mule, láti ọwọ̀ ìjọba tàbí ààjọ-ìsọ̀nà ìlú, yóó jẹ́ nípasẹ̀ ọ̀nà ẹ̀rọ mìíràn.

(3) Asjoú-òfin yóó ríi pé òkọ̀ọ̀kan abˈalọbábọ̀, èyí tí a fi fún-un, yóó wà láàrọ́wọ̀ tó ni àkọsílẹ̀-ìnú ìwé, lórí-ìtàkùn-àyélujára àti ní ẹ̀rọ agbàbùjá kan soso.

(4) Asojú-òfin yóó fí tó Alága àti àwọn olóyè Ìgbìmọ̀ Tẹ́ẹ̀-kó-tó ìjọba ti Ilé-Ìgbìmọ̀ Asojú àti Alága pẹ̀lú àwọn olórí lẹ́lẹ́ka-ò-jẹ̀ka ti Ìgbìmò Atọ́ràn Ìjọba àti Oníidàájọ Ìgbìmọ̀ Asòfín létí, kò sì gbọdọ̀ kọjá osù Igbe nínú ọdún tí abalobábọ̀ náà di títẹ̀e, tí ó sì wà láàrọ́wọ̀tó ní kíkó sílè tàbí nípasẹ̀ ẹ̀ró.

(5) Asojú-òfin gbogbogbòò yóó pile abálọbàbọ̀ àti ọ̀nà àgbàmú-sẹ́sse ní ìbámu pẹ̀lú àbálọbábọ̀ tí abalá yìí n fẹ́ ó sì tún le se ìfílọ́lẹ̀ ohun àmúyẹ fún irúfẹ́ abálọbábọ̀ bẹ́ẹ̀ bí Asojú-òfin bá rò pé yóò dára

(6) Asojú-òfin gbogbogbòò níbi ojúsé rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí aláàbóbútó lábẹ́ Ìsòfin yìí gbọ́dọ̀ ríi pé gbogbo ààjọ-ìsọ̀nà tí ìsọ̀fin yìí báwì se gẹ́gẹ́ bí ó tí yẹ alájọni ó wà láàrọ́wọ̀tọ̀, tí irú ibéèrè bá sì wáyé, ìpìnnu lórí ìbéèrè yìí yóó jẹ́ èyí tó wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí ìsofin yìí fi télẹ̀, àyàfi bí kò sí nínú Ìsọ̀fín yìí.

(7) Asoju-ofin gbogbogbo yoo fi abalọbabọ ọlodọọdun ti yoo jẹ akọsilẹ ọdun to ti kọja ti yoo tọka iye ẹjọ to waye labẹ isofin yii fun igbimọ-asofin apapọ ni deebre tabi ki o to di ojo kini (1) osu karun, awọn oun ti o foju fo mnu ipẹjọ kọọkan, iha ti a kọ si ẹjọ kọọkan, owo-ina, ẹsan ati ijiya ti a bu funni.

(8) Irufẹ abalọ-babọ bẹẹ yoo se ekunrẹrẹ apejuwe aayan ile-isẹ onidajọ lati fi aye gba gbogbo ijọba tabi aajọ-isona ilu ti wọ le tẹ si ipa isofin yii.

(9) Nitori ti abala yii,

(a) “Ijọba” bẹrẹ lori eyikeyi ẹka isakoso ijọba, ẹku ologun, aajọ-ijoba, aajọ agbasakoso tabi ifilolẹ ni eka isakaso ijọba (titi kan ọfisi isakoso aare), tabi eyikeyi ẹka ijọba ti o da duro tabi ti atọna rẹ jẹ ti ijọba tabi ajọ-isọna ilu; ati

(b) “Afọwifun” tunmọ si eyikeyi ọrọ iperi ti a lo ninu isofin yii lati tọka si afowifun tabi akọsile ti o jẹmọ eyikeyi afọwifun ti o wa ni ikawọ ijọba tabi aajọ-isọna ilu ati afowifun ti o fori fun owun ti isofin yii fe nigba ti o ba wa labẹ itoju eyikeyi aajọ-isọna ilu lorisirisi ọna, tit kan ọna ẹrọ.

30. (1) Isofin yii gbero lati segbe, ki sii se lati pa isisẹ atijọ run lori ona ti akosilẹ ilu ati afọwifun, ati wipe ko wa lati se idena fun anfaani ti awọn afowifun labẹ asẹ ti o ma n wa lạrọwọ tọ gbogbo eniyan.

(2) Bi o ba yẹ ki eyikeyi ninu akọsilẹ tabi afọwifun ilu ko wa larọwọ tọ, ti iru ibeere ba si waye, ipinnu lori ibeere yii yoo jẹ eyi to wa ni ibamu pẹlu oun ti isofin yii fi telẹ, ayaafi bi k ba si mnu isofin yii.

31. Nínú Ìsọ̀fín yìí—

“Olùsèbéèrè” ǹ tọ́ka sí ẹni tó béèrè fún àfọ̀wífún làbẹ́ Ìsọ̀fín;

| | |
|---|---|
| “Application” | ǹ tọ́ka sí bíbéèrè fún àfọ̀wífún lábẹ́ Ìsòfin; |
| “Ilé-Ẹjọ́” | túmọ̀ sí Ilé-ẹjọ́ Gíga tàbí ilé-ẹjọ́ Gíga Àpàpọ̀ |
| “Orílẹ̀-èdè Mìíràn” | túmò sí èyíkéyìí orile-èdè mìíràn yàtọ̀ sí Ìjọba Àpàpọ̀ Olómìnira Naìjíríà |
| “Àfọ̀wífún” | àpàpọ̀ àkọsílẹ̀, àkópọ̀-ìwé àti àfọ̀wífún tí a se lọ́jọ̀ ní liana àkọsílẹ̀ ẹ̀rọ, àwòrán aláfojúrí, ìró, ohun gbìgbèsílẹ̀ abbi. |
| “Ààjọ-ìsọ̀nà ìlú” | túmọ̀ sí èyíkèyí ẹ̀ka alúmójútó asọfin, agbófinró, ìdájọ́ tàbí ẹgbẹ́ onímọ̀ràn ìjọbà, tító kan ìgbìmọ̀-pàtàkì, alábójútó-ìsé, onírúúrú ìgbìmọ̀ àti òǹgbàse-ìsẹ́ ti orílẹ̀ èyíkéyìí ẹgbẹ́ asẹ̀gbè tí isẹ́ ẹ rẹ̀ kò pin lórí ìgbìmọ̀ àti àwọn ẹ̀ka ìgbìmọ̀ tí a ǹ fi owó o se ìránwọ́ fún tàbí tí a ǹ náwó ìlú lé lórí àit ẹgbẹ aladáàni tí óń sise sin gbogbo ìlú, se isẹ́ ìlú tàbí lo owó ìlú: |
| “Àkọsílẹ̀ ìlú tàbí” | túmọ̀ sí èyíkéyìí àkọsílẹ̀ tí a ti se kale, tàbí wà tẹlè tabi |
| “Àkòpọ̀-ìwé” | lò rí gba, ní tàbí lábẹ́ èyíkéyìí gbogbo-ìlú tàbí ẹgbẹ́ àdáni tí ó níí se pẹ̀lú ìfẹ́ gbogbo ìlú àti títí kan èyíkéyìí— |

(a) Àfọ̀wífún tí a kọ tàbí fi pamọ́ tàbí èrọ mìíràn; àti èyíkéyìí ohun èèlò tí a rí fàyọ ara àfọ̀eífún tí a gbà sílẹ̀ tàbí fi pamọ́ tẹlẹ̀;

(b) Ìwé ìsàmì tàbí se àpèjúwe èyíkéyìí pá kan, tàbí tí a lẹ̀ mọ ní èyíkéyìí ọ̀nà

(c) Ìwé, páálí, ààtò, ààtẹ-àgbáyé, àwórán-àpẹẹrẹ, atọ́nà-ilà tàbí àwòrán.

(d) Fọ́tò, fìímu, àyísódì, agbakosile fiimu téèpù tabi ẹ̀rọ mìíràn ti àworán abara kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ́ farasin sí kí ó lè(se irànwọ́ pẹ̀lú tàbí láì sí ohun-èèlò.mìíràn).

(e) Lágbára láti tún un gbéjáde.

"Minisítà" túmọ̀ sí Minisítà tí àyànse isẹ́ rẹ̀ jẹ́ ti àfọ̀wífún.

"Person" pẹ̀lú ààjọ kan soso àti àkójọpọ eniyàn yáạ̀ wón dúró bíi ààjọ dá dúró lẹ́yọ-ẹyọ, tàbí siìsẹ̀ pọ̀ bíi ẹgbẹ́ kan soso.

"Personal information"túmọ̀ sí èyíkéyìí àfọ̀wífun làbẹ́ àsẹ tí a ní nípa ẹni àdámọ̀ kan, sùgbọ́n tí kò nì àfọ̀wífún nípa ojúse àwọn òsìse àti onísẹ́ gbogbo ìlú

32. A lè tọ́ka sí Ìsòfin yìí gẹ́gẹ́ bíi Ìwé-ÌsòfinÀfọ̀wífún ti Òminira, Ọdún 2011.

Agbekalẹ Afọwifun ti ominira Odun 2011

| KEKERE RẸ | AKỌLE NLA RẸ | ASOPO OHUN TI O DALE LORI | ỌJỌ TI ITE IGBIMỌ ASOFIN AGBA SỌ DO FUN | ỌJỌ TI ITEMGBMO ASOFIN SỌ DOFIN |
|---|---|---|---|---|
| Ominira fun ọrọ sisẹ ẹgbaa ọdun o le mọkarla | Ise ofin lati mu ki akọsilẹ gbogbogbоо ati ọrọ sisọ wa fun gbogbo eriyal, se ipese fun ọna tiamyn akọsilẹ gbogbogbоо ati ọrọ sisọ yoo fi wa ni ibamu pẹ lu ifẹ inu awyn eniyar ati idaabobo ibi kọlọfin ẹnikọọkar, daabobo awyn osisẹ ijọ ba | Akọsilẹ yii beere lati mu ki awyn iroyin gbogbogbоо ati ọrọ sisọ le wa ni irọwọrọsẹ fun iho gbogbo eniya, se ipese fun ọna lati pese iro yin ati ọrọ, daabobo iroyin ati ọrọ gbogbogbоо de bi wipe yoofi ba ifẹ inu awyn eniyai mu ati idaabobo ibi kọlọfin awyn eniyan, idaabobo | 24TH MAY 2011 | 24TH MAY 2011 |

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| | nipa abamọ ti o le gbẹyin sisọ awyn ọrọ kar sit alai gba asẹ ati lati se idasilẹ ọna asey ọri awyn ero naa fun awyn ọrọ ti o ba jẹmọ. | awyn osisẹ ijọba gbogboo nipa abamọ ti o le gbẹyin sisọ iru awyn ọrọ ti o wa labẹ asẹ bẹẹ sit alai gba asẹ ati lati se idasilẹ ọna aseyọri fun awyn ero naa. | | |

Mo jẹ́rìí wí pé mo ti se àfiwé lẹ́sọ̀lẹ́sọ̀ lórí Ìwé-Ìsòfin yìí ìpinnu Asofin, tí mo sì ríi pé ó jẹ́ òtítọ̀ àti ìpinnu tó péye ti àwọn Ilé-Ìgbìmọ̀ àti wí pé ó wà ní ibámu pẹ̀lú àkòònú Ìsofin Tòótọ̣ Ìsòfin Ìbòrí A2, Òfin Ìjọba Àpàpọ̀ Ilẹ̀ ẹ Naìjíríà.
Ọdún 2004

**Salísù Àbúbákar Maikusuwa, mni**
Àkọ̀wé – Ìgbìmọ̀ Às`ofín Àpàpọ̀
Ọjọ́ 27 Osù Èbìbí, Ọdún 2011.

Ọjọ́ìfòtẹ́lẹ́ láti qwọ́ Ààjọ Ìgbìmọ̀ Ọjọ́ Ìbọwọ́lì láti ọwọ́ ọ Ilé –Ìgbimọ̀ Asojúsúsòfin
Ọjọ́ 24 Osù Èbìbí, Ọdun 2011. Ọjọ́ 24 osù Èbìbí, ọdun 2011.

Mo jẹrìí, ní ìbámu pẹ̀lú abala 2(1) tí Ìsofin Tòótọ́
Ìsofín, Ìbòrí, A2, Ofín Ìjọba Àpàpò Ilẹ́ ẹ Naìjíría, 2004
Tí ó jẹ́ ojúlówó ẹ̀dà ti Ìwé-ósòfín tí a ti ọwọ́ Ilé-Ìgbìmọ̀ Asòfín Apàpọ̀ méjèèji bọ́ wọ́lù

**Salísù Àbúbákar Maikusuwa, mni**
Àkọ̀wé – Ìgbìmọ̀ Às`ofín Àpàpọ̀
Ọjọ́ 27 Osù Èbìbí, Ọdún 2011.

Ìjọ́hẹn 1
**Òmọ̀wé Goodluck Ebele Jonathan GCFR**
Ààrẹ Ìjọba Àpàpọ̀ Olómìnira ti Nàìjíríà
Ọjọ́ 28 osù Èbìbí, ọdun 20011

**Ìwé Ìládìí**
Ìsòfin yìí ń mú kí àkọsílẹ̀ àti àfwífún ìlú tùbọ̀ wà ní àrọ́wọ́tọ́, se ọ̀nà àǹfàní si àkosile àti àfọ̀wífún ìlú, láì yese kure lori ohun ti gbogbo ìlú ǹ fẹ́ àti ààbo olukuluku, daabo bo

àwọn osise ijoba bi won ba yọ̀ǹda àfowifun jẹmo-ile-ise lai gba ase àti itose ti a fi le e fún igbese bee.